OSE KEJE

ISE: YORUBA

ISORI-ISE: ASA ISINKU NILE YORUBA

PERIOD(1& 2)

ASA ISINKU NILE YORUBA

Isinku ni eto ikeyin ti a n se fun oku. Irufe iku ti o ba pa eeyan tabi ipo ti eeyan ba wa nigba ti o ku ni yoo juwee isinku ti won yoo se fun. Nile Yoruba, a kii so wi pe oba ku bi ko se wi pe " Oba waja". Eto isinku oba bakan naa maa n yato si ti eeyan miiran.

Orisii oku meji ni o wa:

i. Oku eko: eyi ni oku agba ti a n se ayeye fun.
ii. Oku ofo: eyi ni oku omode ti a ko le se ayeye fun.

AWON IGBESE SISN OKU AGBA(OKU EKO)

Bi agbalagba ba ku, awon igbese sisin oku bee ni:

i. Itufo: Eyi ni ki a fi to awon eeyan leti wi pe eni naa ti jade laye.
ii. Ile oku gbigbe: Won ni lati gbe ile ibi ti won yoo sin oku si.
iii. Fifa irun okuti o ba je okunrin/ didi irun fun okubinrin: Won n se eyi ki oku le dun wo.
iv. Wiwe fun oku: Won a we gbogbo ara oku bi eni we fun omode.
v. Kikun osun fun oku: Won a fi osun pa lara ki o le rewa.

vi. Wiwo aso / mimura fun oku: Won a wo aso ti o rewa si oku lara nitori Yoruba gbagbo wi pe yoo pade awon eeyan lona.
vii. Sisin oku gan-an: Won a gbe oku sinu ile ti won ti gbe ki won to da iyepe bo o.
viii. Alejo sise: Leyin ti oku ba ti wole, won a fi ounje lorisiirisii bo awon alejo awon ti o wa sibi isinku.

PERIOD(3)

AWON OKU ABAMI ATI BI A TI N SIN WON

Awon oku kan wa ti a n pe ni oku abami. A n pe won ni oku abami yala nitori won ku iku ti ko dara tabi pe won kii se eeyan lasan. Apeere won ni:

i. Asuke / abuke
ii. Eni to jabo lati ori igi ope/ eni ti igi wo pa
iii. Oku omi
iv. Eni ti ara san pa

i. Asuke / abuke: Awon oloro ni yoo sin oku yii sinu igbo oro, leyin ti won ba ti yo ike eyin re ti won si ti se etutu ti o ye. Ikoko nla meji ni won fi n sin won., oku ati ike eyin re yoo wa ninu okan, won a si fi ikoko keji bo eyi ti oku wa ninu re.
ii. Eni ti o jabo lati ori igi ope / eni ti igi wo pa: Awon oloro lo maa sin oku eni naa leyin ti won ba ti gba nnkan etutu lowo awon ebi re, ki irufe aburu naa ma le sele ni idile won mo. Idi igi ti o ku si ni won yoo sin in si.

iii. Oku omi: Awon olorisa omi bii awon olosun ni yoo sin oku re leyin ti won ba ti se etutu ti o ye. Won yoo sin oku si eti odo ti o ku si.

iv. Oku eni ti ara san pa: Awon onisango ni o n sin oku yii sinu igbo leyin ti won ba ti se etutu ti o ye.